**Owe**

Adię iba l'ǫkǫ, ba l'atitan se nkan. Imado iba şe bi ęlędę a ba'lu je, Ęru iba l'ǫba, enia ko ba ti ku ǫkan.

# ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ

**Asoje**

Enia ma jęki t'enia sunwọn, t'eni ma sun-wọn ko ni gbọ Apa ęnọde ko le ka igi Oşe, ylo ma doyika.

VOL. XIII No 686 LAGOS. SATURDAY JULY 1, – JULY 7, 1961. KỌBỌ MEJI (2D)


# MALU ELESE MARUN WOLU EKO, ARIWO TA!

EKO-Ni ọjọ Atalata (Tuesday) ọsẹ yi ni okiki kan kakiri ilu, njẹ kilede ? nwọn ni Malu elenmọ kan ni wọn mu wọlu Ek., gbogbo eṇa si nrọ lọ fi ọnjẹ oju .'oju.

Nigbati a f' jukan Malu na, o ni ẹsẹ mẹrin ti o fi duro s'ori ilẹ, o wa tun ni ẹsẹ kan ti o yọ jade l'oke ẹsẹ iwaju şugbọn ẹsẹ na ko gun dalẹ.

A gbọ wipe Lati ilu Nguru nilẹ Ariwa, l'Oke-Ọya ni nwọn ti mu Malu na wa fun tita, atipe Alhaji A. Y. Ojikutu, Olori awọn Alapata ẹran ni o ra Malu na ti o lọ fi si ile rẹ ti o wa ni 39, l'ọna Apapa, Ebute-Metta, ki ẹnikẹni le maa lọ wo.

A tun gbọ pe Alhaji Ojikutu sọ wipe ati nkan bi ogoji ọdun ti on ti nṣe Apata ẹran Malu, on ko fi oju ri irufẹ e mọ ẹran ayi ri.


**THE NATIONAL BANK**
**Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £3,160,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA.
28 Branches Throughout Nigeria Including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA
ILARO, BENIN-CITY, WARRI
SAPELE ABA KANO, ZARIA, JOS
LONDON OFFICE
15 THROGMORTON AVENUE, E. C. 2
Manager : F. O. Tyrrell.
Telephone : London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEW YORK, PARIS HAMBURG.



**NI IRANTI**
**Iya Wa Owon**

JANE LOKO
Eniti o lọ si ibi isinmi rẹ ni ọjọ keji oşu Keje ọdun 1955.
A fẹ ọ şugbọn Jesu fẹ ọ ju.
Sunre, Sunre, Sunre.
AWA ỌMỌ RẸ


## J. S. TARKA JARE

JOS-Ni ọjọ Alamisi (Thursday) ọsẹ yi ni Adajọ Kotu giga tilu Jos ṣe idajọ lori esun adọte si Ijoba ti Kotu fi Ọgbeni J. S. Tarka ti işe aşiwaju egbe U M. .C dapomo Action Group ati awon isongbe re marun sun, wipe awon ko jebi gbogbo esun mararun ti nwon ka mo won lese. Ni toribẹ, ki nwon ma lo ni alafia.

Ninu idajo re Adajo Ọgbeni V. N. Reed so wipe iwa işelu ni gbogbo ejo na nitcribẹ, ko si eniti a le pe o so otito ni u awon mejeji, Alafisun ati a on ti a fi sun. O soro lori aidogba eri awon eleri Alafisun o si da won sile ni alafia.


Advert. 100
Government Notice No.

NOTICE BY THE BOARD OF CUSTOMS AND EXCISE

Customs and Excise Notice No. 31.

NON-INTEGRATION OF THE BOARD OF CUSTOMS AND EXCISE WITH THE MINISTRY OF FINANCE

"Members of the Public are reminded that the Department of Customs and Excise is not integrated with the Ministry of Finance and that all matters relating to the Board should be addressed direct to the -

Secretary,
Board of Customs and Excise,
Mosaic House,
Tinubu Square,
Lagos
(305/7/60 (5)

Board of Customs & Excise
Mosaic House
LAGOS.
305/7/60
22 June, 61.

**J. M. Idowu**
for the Board

## ORO GBOLOHUN MEJI FUN AWON OKAWE IROHIN ELETI-OFE

Olotu,

Mo ki yin lọpọlọpọ fun aye ti e gba mi lati ba awọn ẹlẹgbẹ mi sọrọ ti gbolohun mejo yin ada'e o. Ọla yin yioo ma lọ soke ni o.

Ẹnyin Ẹlẹgbẹ mi dede, mo ki ayin o, Ẹ ku arọ o, ẹ jire bi? Mo lero wipe p'ripiri ni ara olaka'uka wa mbẹ. Abi bẹ kọ ni ọrọ mi ri. Emi R.A Oriọmọ e Ariyọ fi ulọtufẹ so fun ẹnyin ọkawe Eleti-Ofe wipe:

Mo fẹ lati ma fun Ẹnyin Ẹlẹgbẹ mi ni "Itan Alarinrin" lọsọsẹ pelu owe bi mọwa-mọwa ti yio fiyẹ wipe ti ẹko ba gbọ-ro ọrọ mi ninu iwe lọsẹkọọ, Ẹkọwe bere ohun t'ede lọwọ mi.

Irohin ko to afojuba, Eo ma gbero mi, Eo si mọọ e, lọtitọ Oriọmọpe Akanbi ri mi. Sa ohun to je mi ki Olotu le ma ba mi tete t• jade fun kika awọn Ẹlẹgbẹ mi ki nal ma ri oruko mi nipari iwe mi kọkan.
ki nal ma ri oruko mi nipa iwe mi kọkan.

Mo duro nihin,

Ẹnyin, Ẹlẹgbẹ mi O

O digba die na.

R. Akanbi Ariyọ

Alias — Oriọmọpe

Yaba,

## Itan Owo Alafia Ati Omo

Lati Ọwọ R. A. Akanbi Ariyọ
Alias Oriọmọpe

Itan mi leri awọn ọre meta ti orukọ awọn nje :- Owo, Omọ ati Alafia, awọn meteta ti nṣe ọre bọ ọjọ tipe. Gbogbo eni ti o nri wọn, omo iy.. ni awon npe awọn meteta. Ṣugbon awon ko yi mo agba ninu won.

Nijokan owo pe awon toku re jo o ni e gbo o, Ẹnyin Ẹlẹgbẹ mi bi awon ore wa ba tie bere lowo wa wipe tani ni ẹgbon, ateie ati abikehin ninu wa. Omo ma dahun o ni ewa ni, Alafia ni on wan, owo ni nṣe ni gbogbo ayin npuro, on Ẹgbọn yin re.

Koto ojo koto oju, ni nkan ninu awon ore won ko iwe pe won, wipe awon fe ki awon wa si ibi ik mo awọn. Owo ba pe awon toku re, oni ibi ti awon fẹ lo yi irin ojo meta ni awon ma rin ki won to de ohun.

(Wo yoku loju ewe kerin)


LIVE WELL
EAT WELL
at
"De FACTO"



# OKU'JA WULU

NIGBATI OJA KO BA TA, TI ENITI O NRA OJA KO TA EYITI O RA, BAWO NI YIO TI ṢE LE RA OMIRAN EYI NI OGUN TI ONIṢOWO LE ṢE TI OJA RẸ YIO FI MA TA BI IṢU AKARA GBIGBONA.

Eleti-Ofe

E MA KA IWE IHORIN ELETI-OFE


# AKOKO OJO IBI OBA L'OJU OMOBA ANDREW



Eyi ni Aworan Alaiyeluwa Oba Obinrin Elizabeth Keji pelu ọmọ ịrẹ ọkunrin kekere, ọmọba Andrew to o wa lọrọ Alaiyeluwa lori oke Afin ọla Bucking han nilu nla London, lẹhin Alaiyeluwa ti gba ijuba awọn ọmọ Ogun nibi ọjọ ibi rẹ.

# E MA SE KANJU JAIYE, E DURO DE ASIKO OLUWA

Lati Qwq Latifu Akintunde Babalola Alias Oluwa Lowi

Mo ki ẹnyin Okawe Irohin E'eti-Qfẹ kakiri agbaiye E ku inawo ọsẹsẹ, Ọlọrun ko ni fi kọbọ meji wọn yin mo ri ton nibiti ẹ ti nmu ẹ ko ni lugbadi ọmọ araiye. Ọpọlọ ti ẹ fi nka iwe na ko ni daru mọ yin l'ẹgbari, mo si tun ki Olotu iwe na, Ọlọrun yio ma fi imọ kun imọ yin, ọkọ ọba ko ni ṣa yin lẹsẹ, mo ki gbogbo ẹnyin oṣiṣẹ iwe na ẹ ku iṣẹ o, Oluwa yio bo gbogbo nyin laṣiri ẹ o ma ri ṣe, ajinde ara yio ma jẹ itẹlẹ yin ko ni bi ẹmọ araiye ninu, idagiri oru ko ni da ẹni kankan yin Oluwa yio wa pẹlu wa, amin.

Ẹhin Okawe irohin Eleti-Qfẹ, mo ti mura silẹ lati ma fi itan aladun ati lati ma fun yin ni ọrọ iṣiri tabi ni ima gba yi ni imọran ẹrọ mi osẹ yi ko ni pọ pupọ.

Ọrọ mi t'ọsẹ yi yio jẹ lori gbogbo awọn ti nwọn nkanju jaiye nitori aile duro de asiko Oluwa mo bẹ gbogbo enyin ọkawe mi yi lati ni suru de asiko Oluwa ti ẹ ba de ile ẹjọ, ẹ o ri pe ogunlọgọ awọn enia lode aiye oni ti di ero ẹwọn kilo fa ? nitoriaini suru nipa kikanju jaiye lati lọ jale tabi yiyi iwe owo pada.

Ọjọ wo ni ẹnyin kawe Irohin ti ojojumọ tabi ti ọsẹsẹ lede Oyinbo tabi ede Yoruba ti ẹ ko ri pe wọn ju lagolo ja si ẹwọn, nitoripe o lọ jale tabi o lọ yi iwe wo bẹ ni iru iwa bayi ko dara, eyiti o tun wa buru oju ninu rẹ nipe lati ma gbe ọmọ olomọ lati ma lọ fi şe'ṣọ, mo bẹ ẹnyin Ọkawe irohin Eleti-Qfẹ, ẹ jẹ k'a ro ni suru, ẹniti o nisuru gbogbo ohun lo ni, bi o ba ri pe ni'ori ẹgbẹ rẹ nkole, o nra moto lo nṣe ẹ, ti o ko fi ni igẹlorun si ipo rẹ, jọwọ ṣe iranti pe ika owo mẹwa ati ti ẹ ẹ ko dogba, kadara ni gbogbo nkan, o ni ohun ti o ti ba ẹlẹda rẹ so ki o to wa si ile aiye o.

Nigba wo ni ẹnyin de ile ẹjọ ti ẹ ko ba oganlọgo omo enia ni-aju adajọ fun ẹsun ole, jibiti, ọlọṣa, Alọnilowogba ati fun iwe yiyi pada kilo fa ? o fẹ kanju jaiye laiko to asiko ti ẹlẹda rẹ yan fun u tabi lati le ẹni iwaju ba.

Nitorina mo bẹ yin, ẹ lo ni suru e ma şe kanju ju asiko Oluwa lo.

Lo se to mbọ lagbara Ọdua, ẹnyin yio ma gbadun mi siwaju si. Ao pade ara wa l'ayọ o. Amin

# OLE OJUKOROJU, ENIA MARUN W'EWON

ONISHA-- Enia marun, Paul Chukwu, Samuel Okenwa, Peter Igwe, Peter Okoli ati Chukwu Ezekiel ni adajọ Kotu ilu Onisha ju s'ẹwọn oṣu meji-dinlogun fun ẹnikọkan fun ẹsun ole jija.

Awọn ọdaran eyi ti na ni awọn ọlọpa pe ni ogboju ọlọṣa ti o nja ni ọsan gangan nwọn si ti nṣe ẹwọn nigba pupọ. Nwọn pade Ọgbẹni Joseph Egbuche Nnoli ni ọjọ kẹta osu April ọdun yi, ni ọsan gangan, nwọn si ki mọlẹ nwọn ji owo ọgbọn pọnun ti o wa lọwọ rẹ ni ti ebu e Onitsha.


CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENT
IKORODU TRADING COMPANY
20, & 28, Balogun Street, Lagos.


# Ajakale Arun Tun Nfarahan

Agbọ irohin wipe enia mẹta-din-ladọta ni ajakalẹ arun ti pa, o si to ẹgbafa enia ti ajakale arun na ti kọlu nilu Philipine lati ọjọ kẹta oṣu June, gẹgẹbi irohin ijọba ti wi. Ṣugbọn awọn enia nsọ wipe awọn ti arun na ti sọ d'ẹku ọrun to meji-din-logorun

Ajakalẹ arun na, jẹ irufẹ eyiti o ja ninu ọdun 1957 ti o kari aiye lati ilẹ Aṣia wa, ni a tun gbọ wipe yio tun goke de aye rẹ ninu oṣu ti o mbọ.

Şiṣọ mbẹ ni ọdọ Ọlọrun.

# IWE IROHIN ELETI-OFE NGOKE AGBA

Afi ọpẹ fun Ọlọrun, ati iyin fun Anabi Muhammed (Salalau Alehin wasalam) lori Iwe Irohin Eleti-Qfẹ ti ndi ọmọ ọdun mẹrin'a ti o ti tun bi s'aiye ni ọjọ kọkan-le-logun oṣu June, 1961.

Ninu Ofin ati ọlaa ti o mbẹ ninu iṣẹ Iwe Irohin, enu wa ko gba ọpẹ fun Oluwa Olodumare ti o gbe wa rekọja gbogbo idera na laini if'arapa. Adupẹ a tun ọpẹ da o.



In half a century
two million Olivetti machines
have done the writing
all over the world.
With this experience
**Olivetti**
has created the new office typewriter
with integrated carriage,
the
**82 Diaspron**
The same qualities as always
but intensified and improved.
The same capacities as always,
with new and different features added.



Distributed by
**LEVENTIS TECHNICAL**
Available at
**Leventis** Marina, Iddo, Ibadan, Kano,
Kaduna, Jos, Port-Harcourt, Aba.


# E MA KA IWE IROHIN ELETI-OFE




A GIFT FROM HEAVEN!
BAMWO BABY MIXTURE
OF EXCEPTIONAL VALUE IN PREVENTING SICKNESS, CURING FEVERS, COUGHS, MEASLES AND TEETHING AILMENTS. ENSURES SOUND SLEEP.
PRICE 2/6 POSTAGE 1/-
THE EGBA TRADING ARADAN STORES, 144 DENTON STREET, P.O. BOX 2 EBUTE-METTA & BRANCHES


ORO OLOTU

# OHUN ENIA NI OHUN OLORUN.

Bi oro na wi ninu iwe mimo Bibeli- gbolohun ti a fi şe akolo oke wosika wa ose yi je edo oro ti a nilati fi şe eko, ki a si maa şora nipa oro siso jade l'enu wa nitoripe Olorun ko mo oro ti a nfi ş'ere yato si oro otito ati ododo.

Awon Yoruba monimoni fi se owe pa fun wa lati fi koni l'eko wipe, "Owo ara-eni ni a fi ntun iwa eni şe." Benani oro ti a nso si ara-eni je, gege bi awon ojogbon Yoruba enia ti so wipe, Areta ko nfi arare şepe," nigbati o bo dari lati oko ata ti o lo re, ti o mbo wa sile, bi enia ba ri ti enibe si kii k'abo pelu ibere wipe, o rire tabi o ko rire? yio f'esi dalohun pada wipe, on ko rire o, nitori ki enia na ba ma ba le toro ata die lowo re.

Nitori na, awa eda enia ni isora pupo nipa oro enu wa, yala si arawa tabi si awon omo wa, tabi si e ikeni nitoripe jebe ni ti Olorun Eleda wa, ko si si eniti o le mo igbati awon Oguo-osun tabi awon Malaika yio wipe ki o jebe.

Bi enia ba nri je ti o nri mu, ti o si tun mbo awon enia die kan mbo lati owo enibe, ojo ti oluware ba la enu ti o wa l'agbari re so wipe on ko ni şe iranlowo fun awon enia na mo, nitoripe nwon ko mo ore fun on, ojo na ni Olorun yio ge ibukun enibe kuru ti yio fere le maa fi agbara wa ohun ti yio to fun on nikan lati je.

Nigbamiran a o tun şe alaye lori gbolohun "ohun enia ni ohun Olorun" fun enyin okawe wa.

## Itan Owo Alafia Ati Omo

(O bere loju ewe keta)

Owo ni ki e fi le mo pe on ni (ega agba) o wo ni ki nwon ma lo, o ni ti o ba di ijo keji, on a ma bo lohun, on a si ba won lohun, on a si ba won lona. Omo ati alafia ni iro ni. Nwon pariwo le owo lori.

Owo bada won lo un o si ti o ba se wipe tiyen so ni rin de idaji ona ti nwon ma fi bere Emi Owo awon ni iro ni, ni won ba nlo nigbati o di ijo keji, owo gbera nile o nlo si ibiti ore awon tipe won.

Omo ati Alafia ti nrin irin ojo keji loju ona. Ebi bere si pa awon mejeji, nwon yan on jeun, eyi omo je :- Iresi ati Eja tutu alafia fe Amola pelu Eran gbe Nwon yo awon wa ki Iya olonje wipe odigbose o.

(Iyoku di ose tombo)


**Plushes, Velvet, Velveteens, Damask & Building Materials**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street, (Faji Market)

LAGOS NIGERIA

The House Where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Company., 24, Kosoko Street P. O. Box 461 ... Phone 22370